Oja kota!
Em\ Polo-
wɔ Ojo yin
Sinu Iwe
Irohin
Imɔle

IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

NOW ON SALE
M a b a y o mi je Oluwa Calendar 1962 6d Copy 4/-6d Dozen.
OPE — OLUWA PRESS,
36, Abeokuta Street
EBUTE — METTA
LAGOS.

VOL. V No. 304 MONDAY OCTOBER 30 — NOVEMBER 5 1961 KOBO MEJI (2d

# Ẹniti o ja Ọlọrun ni ole, Ọlọrun ki mọlẹ, o dajọ fun

LẸNU LỌLỌ YI NI AWỌN ỌLỌPA SỌ WIPE, ỌDẸLẸSINRIN KAN WỌ ILE IJỌSIN NIBITI IJỌ BAPTIST TI SURU-LERE GBE NSIN ỌLỌRUN, WỌN SI KO GBOGBO AWỌN OHUN ELO IJỌSIN LỌ, A KO SI RI ẸNITI O MỌ OLE NA.

A gbọ wipe ọkọ Reluwe pa Ọkunrin ọdẹlẹsinrin kan si teṣọn Ikẹja ni alẹ ọjọ ti ole ja, ni ninu Ṣọṣi Ijọ Baptist, a gbọ wipe nṣe ni Ọkunrin na ji ọkọ wọ.

Ẹ o ri i, Amokunkun sole, ti o wipe Ọba aiye ko ri on, njẹ bi Ọba a i y e ko ri ọ nkọ, Ọba Ọrun ko ha nwo ọ bi. Ọkunrin ti o gboju-gbaiya wọ ile Ọlọrun ti o ro wipe Ọlọrun ko le sọ kalẹ wa mu on, ẹ o ri wipe Ọlọrun ko nku, ẹsan ko ngbe, odu ifa kan sọ bayi pe, Ẹni buruku nsa lọ kuro loju Olodunmare, Olodunmare ni ẹ mu, ẹ mu, ẹ mu.

Takute Ọlọrun, ko si ẹniti ko le mu, ẹ n i t i o ja Ọlọrun ni ole, Ọlọrun ki mọlẹ o dajọ fun.

**A gbọ irohin lati ile Meka wipe, lilo ti awon ara ile.** Naijiria nlọ si ilu Mẹka lọdọdun lati lọ ṣe Hadji fun Ọlọrun jẹ, eyiti o jọ Ọba Suudi ọmọ Abudu Lasisi loju tobẹ gẹ ti o fi ran ọkan ninu awọn a s o j u rẹ, lati wa ṣe atipo (Ambassador) ni ilu Eko, ki o le ma gbọ bi irohin Ilu yi ti nlọ si.

## Won Tu Igbimo ibile Egba ka

Alhaji D. S. Adegbero, Olotu ipinlẹ Iwọ-Orun ati Alaṣẹ Igbimọ ibilẹ, tu igbimọ ibilẹ ẹgba ka eyi ti o ṣe pe ẹgbẹ Afẹnifẹre (action Group ni o npa aṣẹ Igbimọ ti o wa fun agbegbe Ẹgba na.

Lẹhin ọjọ mẹrinla ti o ti fi ẹsun kan awọn ọmọ ile igbimọ na, nipa aiko ṣe iṣẹ wọn dede, Olotu Ijọba na s i n ti y a n awọn enia mẹrindinlọgbọn dipo wọn, ti yio ma ṣe eto ile igbimọ na titi a o fi yan awọn Ọmọ ile igbimọ tuntun miran.

Ọba Alake Abeokuta ni yio ṣe Olori awọn enia mẹrindinlogun ti yio ma ṣe eto ile Igbimọ na.

Ikede kan ti o ja de lati ile iṣẹ Olotu I j ọ b a Ipinlẹ Iwọ orun fun I g b i m ọ ibilẹ sọpe ajẹlẹ ipinlẹ iwọ orun na si ti fi ara mọ wipe ki a tu i g bi m ọ na ka nipa pe awọn igbimọ na ko ṣiṣẹ wọn bi o ti tọ ati bi o ti yẹ fun alafia awọn enia ti mbẹ ni agbegbe wọn.

WO IYOKU NI OJU EWE KẸJỌ

## Oloye Ayo Rosiji se ase repete fun egbe Olope



Oloye Ayọ Rosiji ati Iyawo rẹ ni a gbọ wipe o ṣi ile titun kan si Oke Apapa, eyiti a gbọ wipe nwọn ṣi ile titun na, ni ọjọ ti a nṣe ajọdun ọdun kan ti Ilẹ Naijiria gba Ominira. Ninu aworan oke yi ni, bẹrẹ lati ọwọ osi, Oloye Ayọ Roṣiji, Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Ọlọla Abubakar Tafawa Balewa ati Lord Head aṣoju ilẹ Gẹsi ni ilẹ Naijiria.

# Ọrọ Olotu

## Enu kan ni a fi nko omo ko le logbon lori

A ki gbogbo ẹnyin Onkawe wa, ẹ ku owurọ, ẹ o jire bi, lọsẹ to kọja a sọrọ nipa mọto wiwọ loju ọna, ko yẹ ki o ja si owo. Ṣugbọn lọsẹ yi, iwaṣu wa ni, nipa bi a ti le kọ ọmọ eni lọna ti o tọ ati ti o yẹ, ki a to bẹrẹ si ọrọ na, a fẹ ki gbogbo ẹnyin Obi ti ara balẹ ka ọrọ na dada, bi ẹ ba si tẹle ọna na yio ṣe yin lanfani.

Ẹniti o ba nfẹ ki ọmọ on lọgbọn lori, ẹnu kan ni a fi nkọ ọmọ, ṣugbọn nigbati Baba sọ fun ọmọ rẹ pe, Iwọ ọmọ yi, nko gbọdọ ri ọ lode gbangba lọla, ti iya ọmọ na da lohun wipe b a w o ni o ti ṣe sọ pe ki o ma jade, nigbati ki ṣe ọlẹha, ki ni ohun ti o fẹ ki o ma ṣe fun ọ n i l e, Iwọ A y ọ k a bọ sita ki o ma lọ sere rẹ

Bi enia ba nkọ ọmọ bayi, ọmọ na ko ni jẹ enia atata lẹhin ọla, ẹnu kan ṣoṣo ni a le fi kọ ọmọ ẹni. Kilọ fun wipe ko gbọdọ jade sode, ohun ti o yẹ tabi ti o tọ ki Iya ọmọ ṣe ni wipe, o yẹ ki o tun kan nipa wipe, afara ko lọ gbe iwe rẹ, bi mo ba ri ẹsẹ rẹ lode, tẹtẹ yio jẹ ọ.

Iru ọna bayi ni awọn Obi ti nfi ẹ n u kan tọ ọmọ wọn. Ọrọ Ọlọrun kan sọ bayi wipe, "Kọ ọmọ rẹ ni ọna ti o tọ, nigbati o ba ṣi wa ni ewe" nitoripe bi o ba dagba tan ki o ma ba ya kuro loju ọna na.

Nitorina a wa Oniwe Irohin Imọlẹ bẹ gbogbo ẹnyin Obi tabi Alagbatọ lati ma kọ awọn ọmọ nyin ni ọna ti o tọ, ki ẹ si ma panu pọ kọ wọn, ẹ n u kan ni a fi nkọ ọmọ ni ọna ti yio tọ nitori ẹhin ọla.

---

## Eniti awon Omo ile Eko titori re fe ko ile Eko sile



Irohin kan wa wipe, awọn ọmọ ile-Ẹkọ Lagos City College ti o mbẹ ni Yaba fun awọn Alabojuto ile Ẹkọ na laye ọsẹ meji lati fi ohun ti nwọn fẹ si ero.

Ohun ti a gbọ ti awọn ọmọ ile ẹkọ na nfẹ ni wipe, ki Ọgbẹni Tunde Lawrence tiṣẹ igba keji Olukọ Agba fi iṣẹ Olukọ silẹ, ati gẹgẹbi ohun ti awọn olukọ jiroro larin ara wọn nipa ọrọ na lo ịnu ki awọn ọmọ Akẹkọ na pada sile ẹkọ.

Ẹniti a nwo ninu aworan oke yi ni Ọgbẹni Tunde Lawrence, ẹniti nwọn ko fẹ larin awọn Olukọ ile-ẹkọ Lagos City College mọ.

## Esi Oro Omo Arindegbaju.

Lati Ọwọ ;- SISA ẸKUN TO JO KO.
O BERẸ LATI ỌSẸ TOKỌJA

Ọmọ Aridegbeju tun tọka si wipe awọn kori wọn ni 19, Ijaye Street l'Eko nile Alhaji Ọjọmu eyi le ri be, ohun ti o si fa ni wipe awọn ọmọ Ilu Oro kise a da nkan ru, bi o si ti je wipe ẹmi ọta lọwa lọkan Ọmọ Aridẹgbaju si awọn Ilu Oro, bi o si ti jẹ Ọmọ Aridegbaju ti jẹ ọkan ninu awọn to nlọ ipade Ile Alahaji Ojomu yi si le sri tẹ awọn asoju Ilu Oro torun, nipa be yio dara ki wọn si f,are sokun titi ti iru awọn Alhaji Ọjọmu ati awọn patakipataki ọlogbọn ati oloye miran ti wọn nlọ ipade ile Alhaji Ọjọmu yi yio fi mọ awọn adaluru pọ mọ sapa yatọ si awọn enia to nfẹ ilosiwaju Ilẹ Igbomina. Eyi si ti nfara han diẹdiẹ, nitoripe Ọmọ Aridẹgbaju papa ko si ni ti ri ka ninu iwe Irohin (Daily Times) pe ọkan ninu iru Ọmọ Aridẹgbaju yi ni wọn yọ kuro ninu Ẹgbẹ N. P. C. (Ilọrin South) laipe yi.

IYOKU DI ỌSẸ TO MBỌ

---


## Nigerian Ports Authority

### Invitation to Tender

CONTRACT FOR SUPPLY OF LABOUR FOR

(a) No. 9 BERTH, APAPA QUAYS

(b) NO. 9 TRANSIT SHED APAPA QUAYS

The Nigerian Ports Authority invite tenders from Contractors to supply experienced labour with adequate supervision for the handling of cargo at the No. 9 Berth, Apapa Quays.

2. Tenders which must be submitted on forms provided by the Authority and returned in sealed envelopes marked "CONFIDENTIAL-TENDER FOR LABOUR" should be addressed to the Secretary to the Authority Nigerian Ports Authority, 216, Broad Street, Lagos, so as to reach him not later than 4 o'clock in the afternoon of 15th November, 1961.

3 The issue of an official form of tender will be subject to a deposit of £10, payable to the Authority's Cashier, Accounts Department, Apapa Quays. The deposit will be returned on receipt of a bona fide tender.

4 Applications from only labour contractors who have had experience in similar work will be considered, and the Authority do not bind themselves to accept the lowest or any tender.

*BAYO KEHINDE*
*Secretary to the Authority*

N. P. A. Notice No. 639.
23rd October, 1961.


---


## Iwo ha Nfe I g b e g a bi?

Fun anfani awọn ti o ngbe Eko, ti ko le mọ ile iṣẹ wa ni Mushin, ni aṣe kọ awọn apakan ninu ọja wa si Nọmba 16 Bamgbose Street Lagos, ẹnikẹni ti o ba fẹ ra ọja wa ni Eko ki o ma lọ sibẹ.

TURARI AJẸBIDAN AGBABIETU

Turari yi ko ni ẹgbẹ akosa fun awọn ajẹ ni, ti o ba nloo iwọ ko ni mọ a i t a ọja. Adura rẹ yio si ma a gba Awọn enia buruku aiye ko tilẹ ni lagbara lori rẹ onṣiṣẹ to igba ọna (200 ways) fun igbega ọmọ enia ni ilẹ A i y e. (Pangolo 10/6d)

MANAGER (J. O. SHOYINKA.) c/o IROHIN IMỌLẸ 16, BAMGBOSE STREET, LAGOS.

# *ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE*

## Riro ni ti enia, sise ni ti Olorun

Lati Ọwọ:- Fatai A. Oyerọgba (Bonny Gaspa)
No. 18, Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye.

Ni igba Iwaṣẹ, Baba kan wa, o jẹ olowo n i l u rẹ, o wa ọmọ fun ọdun diẹ, ti Olọrun ko yọnda fun, ṣugbọn nigbati a s i k o to lọdọ Olọrun, o fẹ Iyawo kan, o si bi ọmọ kunrin kan ati ọmọ binrin kan fun u, eyi ọkunrin ni ẹ g b ọ n, nigbati asiko ati sun to fun baba, ṣe Onişegun kan ko ri ẹbọ iku ṣe, bẹni Babalawo kan ko ri ara rẹ loju ọpọn, baba olowo yi ku, ọjọ kẹdogun isinku b a b a yi ni wọn pin awọn ohun ini rẹ fun a w ọ n ọmọ ti o fi s i l ẹ saiye lọ, ogun to kan ọkunrin yẹn jẹ Ọkẹ-mẹwa ponun, ọmọde yi gba gbogbo owo yi, o lọ ra awọn nkan mere-mere fun tita (Wosi-wosi) o to gbogbo awọn ọja wọnyi si ori atẹ, o gbe wọn ru o wa nlọ si ọja, ni ọjọ kan nibi ti o ti duro to ngbero pe ti mo ba ta ọja mi yi tan, gbogbo owo mi yio jẹ ogun ọkẹ, bi mo ba tun ta tan yio jẹ ọgbọn ọkẹ, o ni ti on ba ta titi ti ere (Profit) on ba to Ogoji Ọkẹ, on yio lọ fẹ ọmọ Ọba Ilu, ti on ba lọ fẹ, ti o ba sọ pe on ko gba, ti Iya rẹ ba wa on ko ni gba ẹbẹ wọn, aya fi ti Ọba Ilu ba wa.

Njẹ ẹ ko mọ pe, eleyi ti kọja aye rẹ, ti wọn ba ti lọ si ile wọn tan ti o ba wa mbẹ on, tabi ti o ba gbe onjẹ siwaju on, Emi si sọ pe, Iwọ ọmọde yi, o ko iti fẹ ọmọ na, imọran rẹ ti pọ to bẹ, nibiti o ti nsọ pe, on yio gba Lẹpa pe, kuro niwaju mi, ko ranti pe ọja olowo iyebiye wa lori on, gbogbo rẹ si danu, nibẹ ni Iya kan ti o wa nitosi ọdọ rẹ wa da hun pe, Iwọ tapa si ọmọ Ọba, pataki Ọba, anfani rẹ ni iwọ ri yẹn.

Ọmọ kunrin yi dọ ọ balẹ fun Iya na, o dupẹ lọwọ rẹ fun anfani ati ikẹdun ti o ni si on. Eyi kọ wa pe, ki a ma ṣe dawọ le ohun ti o ba ju wa lọ. Mo juba awọn Agba, ko jẹ ki aiye yẹ wa o

## Awon Olopa ile Gambia lo be ile ise Bicycle wo



Awọn enia Dudu meji ti a o nwo ninu aworan yi ni, awọn Ọlọpa ilẹ Gambia meji ti wọn lọ kọ iṣẹ ni ilu Oyinbo ti wọn si lọ ṣe abẹwo ileṣẹ ibiti wọn gbe nrọ Kẹkẹ (Bicycle) Rali ni Ilu Oyinbo.

Ẹniti o bẹrẹ ni ọwọ osi ni Saji Majọ Kikala Bande, Oyinbo meji ti o duro ni arin meji wọn ni T. G. Okland, Ọ l ọ p a ilu Oyinbo ati Saji Usman Bojang.

## Kini O mo Nipa Iwo Oruu Afrika?

(1) Iru Owo wo ni awọn Oyinbo Alawo funfun mba awọn enia wa ṣe nigbati wọn wa si Iwọ orun Afrika?
(2) Tani Oludasilẹ Ẹsin Islam?
(3) Darukọ ọmọ Naijiria to gun Alupupu (Motor Cyicle) kakiri Agbaiye?
(4) Tani O l u k ọ Agba Ilẹ Ẹkọ Giga University ti Ilu Ibadan?
(5) Darukọ ẹniti o da aṣa pe ki ama pa awọn Ibeji mo duro duro nilu Calabar?
(6) Darukọ Olu Ilu India (Capital?)
(7) Ọdun wo ni wọn kọ kọ, kọ Ile Isin Church) si Ake, Abẹokuta?
(8) Ọdun wo ni ọkọ awọn Potoki (Portuguese) wọ etido Ilu Benin?
(9) Ọdun wo ni wọn si Ile Ẹkọ Giga ti nwọn npe ni Higher College ni Yaba?
(10) Tani a fi joye Gomina Ipinlẹ Gusu ati Ariwa Naijiria li Ọdun 1912?
(11) Sọ ilu pataki meji to gbajumọ fun owo siṣe ni agbegbe aṣalẹ Shahara?
(12) Tani o gbe ilu Eko le awọn Gẹsi lọwọ? (b) Lọdun wo ni?
(13) Darukọ ilu meji ti wọn ti nda awọn Ẹru silẹ ni iwọ orun Afrika?
(b) Lọdun wo?
(14) Tani Baba Ẹgbẹ ilẹ Amerika Kẹrindilogun?
(15) Nibo ni awọn Ẹru ti nşişẹ nilẹ Amerika?
(16) Nitori kini asia orilẹ ede Amẹrika fi ni Irawọ Mejidilatọta (48) Lara?
(17) Ilu bo ni a ti le ri awọn odo wọnyi:- [Niger ati Benue,] Orange, Amazon.
(18) Ilu bo ni wọn ti ko awọn ikan wọnyi wa:- Ẹja Panla, I ş a n a, Owu Siliki, Kẹkẹ olo gere.
(19) Kini awọn Oyinbo nfi nkan wọnyi se? Cocoa, Epo Pupa Rubber, Ẹpa
(20) Kilo se ti ako fi gbagbe ọjọ Kẹrindilogun Oşu Kọkanla, Ọdun 19 60

WO IDAHUN AWỌN IBERE WỌNYI NI OJU EWE KEJE.

## Itan awon Omo Iya meji

Lati Ọwọ:- A. O. Emanuel Ọlawale.
No. 10, Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye.

Ni ọjọ kan awọn ọmọ Iya meji kan wa, ikan Ọkunrin eyi ekeji jẹ obinrin, Baba ati Iya wọn jẹ Olowo. Nigbati o ya o pe awọn mejeji pe, iṣẹ kini wọn ma se? eyi Ọkunrin ba da hun pe on yio si ma ro na, eyi obinrin ni aṣọ ni o wu on.

Ni Baba ba ko Ogoji pọun (£40) fun ki o ma ba ti rẹ lọ, eyi Ọkunrin ni iṣẹ Agbẹ ni o wu on. Ni baba tun fun ni Ogoji pọun a t i ogoji ṣile (£40 40/-) on na ba ko tirẹ lọ. Nigbati o de ilu kan, o ri awọn oni Tẹtẹ o ba fi ogun pọun ba wọn ta, ko jẹ rara, eyi obinrin ba fi owo tirẹ da kowo aṣọ, eyi ọkunrin ti na tirẹ tan, o wa nrin kiri ko da oko rara ninu rẹ.

WO IYOKU NI OJU EWE K E J E

# SE BOTIMO (APA 5)

Lati Owọ:- FUNMILAYỌ KOFOWOROLA

AKIYESI PATAKI FUN AWỌN OLUKA ITAN MI.

Ẹjọwọ ẹ mase binu pe ẹ ko ri (apa 5) itan mi ka ni ati ọjọ yi ni a iko ri ayẹ to ni ko jẹki le ko ọ, ṣugbọn nisisiyi lọ ti Oluwa ko ba fi amodi ṣe ara, ọsọsẹ ni ẹ o ma ka Itan na.

Ibiti mo sọ itan na de ni ibiti Iranlọwọ ti fa Ṣebotimo fun O k u n r i n kan, ti o si fa Nini-owo-kogbojubọro fun Obinrin arẹwa keji.

AWỌN MEJEJI DAGBERE FUN ARA WỌN

Ki olukuluku to tẹle iko rẹ, nwọn da gbere fun ara wọn, Ṣebotimọ ni, Nini-owo-kogbojubọro arakunrin mi ọwọn, nihin ni ipinya yio ti de ọpẹ ni fun Eledumare jọwọ maṣe gbagbe ohun ti a mba lọ, biko ba ṣe imọ wa tiko papọ ni, ọna kanna ti a ba jọ ma a tọ lọ, tẹlẹtẹlẹ ironu ko papọ, " Ohun ti o wu mi ko wu ọ, ni i jẹki olukuluku ma a jẹun wọn lọtọtọ" toto o ṣe bi owe, ni kukuru okan ti o wa lọ ni ki o dojukọ o, bi ọwọ rẹ ba si ti tẹẹ, ma jafara ki a le jijọ pade lẹnu ibode yi ti a pinya, ki a si jọ ko ere oko dele.

Oluwa alanu yio jẹki riri wa o ku o, o kọ ni ko agbako ọna, agbako ko ni ko ọ, Idamu ki-damu yio wu ki o ba pade lọna Oluwa yio maa fi iṣọri rẹ ṣọ o.

NINI OWO KO GBOJUBỌRỌ FUN L'ESI

Sebot mọ, osẹun, seun bẹ ni ọrẹ O d o d o nṣe, emi ni temi o, mo ti pinnu lọkan mi pe ibikibi ti o ba le jasi ni temi, ki nsa ti ri owo jaburata Ṣeb: lọju rẹ ni mo ṣe nje wọ fun Iranlọwọ pe nko kọ lati sin lẹru, ki nsa ti l'owo. Nitorina mase fi oruko Ọlọrun gbadura fun mi mọ afi oruko eṣu.

Nitoripe owo Odọ. Ọlọrun ki wa kiakia, afi ti eṣu, ti o ba r e t i mi ni bodeni ọgbọn ọ j ọ oni, ti oko ba ri mi ki o mọ wipe mo ti fi ile eṣu ṣe Igbugbe niyẹn, maṣe ronu ni pa mi mọ yara mu ọna wa pọn nitoripe ohun ti o ba wu ọmọ jẹ ki i run ọmọ ninu, ki nma ba ọrọ gun lọ titi, ayọla o fi pade ara wa o, awọn mejeji si ara wọn lọwọ ni wọn ba Olutọna wọn lọ.

Sebotimo ati Olutọ rẹ gba apa ọtun Nini Owo ko gbojubọrọ gba apa osi ni olukaluku ba gba ọna tirẹ lọ.

Akiyesi:- L ọ s ẹ to mbọ logbara Ọlọrun ẹ o ma ka (apa 6) adun pupọ, ẹmase gb gbe lati ra I r o h i n Imọlẹ.

---

## Surulolere Anjorin Omo-oke Imale ni OMUPO

Awọn ti a daruko rẹ soke yi ṣe ipinnu lati ṣe ere nla aladuno kan ti o miringindin nillu Eko ni Lagos Public School, 2, Eletu Iwaṣhẹ Street ni dede agogo mẹjọ alẹ titi di meji oru. (8 p. m. - 2. a. m.)

Eniti yio ṣe ere na ni ọkunrin olokiki kan ti gbogbo aiye npe ni ALABI IKỌTUN, ELERE ỌBA ILỌRIN.

Owo Iworan jẹ Ṣile marun, ati Ṣile mẹta. (5/- & 3/-)
Awọn ti a ba fi iwe pe, a o gba owo iyi lọwọ wọn ni ẹnu ọna.

A le ri iwe iworan na ra lọdọ MALAM KADIRI IYANDA 36, Bankọlẹ Street, ati lọdọ Alaga wa Alufa Idrasa 78 Ojuagbara Alley. Asi tun le ri Iwe iworan ra ni ẹnu ọna ile ere na.

Nwọn o ṣe ere na ni ọjọ 5th. oṣu November 1961 Iru ere ti Alabi Ikọtun na yio ṣe jẹ ijo agbe alarabara pelo ohun ti o dun, lati Ilọrin ni elere na ti mbọ wa

---

## Owe Ajapa.

Ajapa pe ọmọ rẹ, o wi pe, bi mo ba lowo, ngo ra Ẹṣin kan, oluwa rẹ yio simi aborọ fi ẹsẹ sanle lo si oko. Ọmọ Ajapa dahun pe, Kai! Baba mi fẹ ra Ẹṣin ngo gun u bayi, Kutupa! Kutupa! Ajapa lọ bosi igbẹ fa kumọ yọ, o la mọ ọmọ rẹ lori o wipe, ofẹ pa Ẹṣin mi.


SỌRA FUN

OTUTU IBA










DỌKITA SỌ WIPE




Da OTUTU IBA rẹ duro

gbe koro "ASPRO" meji mi

ARA RẸ YIO SI TUN YA-GAGA

# IGBESI AIYE MI NINU IGBO AILOPIN (APA 7)

Lati Ọwọ:- Simeon Adegoke Fatoki

Nigbati mo si tun ri Ọba wọn mo fi ori balẹ fun nitoripe enia ko tilẹ mọ pe aditi ni rara. O wọ aṣọ Alagba ti o dara, o si jọ arẹwa enia. Nigbati a de ọdọ rẹ awọn Iranṣẹ yi fi ẹnu ko ni eti wọn si sọ ọrọ jẹjẹ fun lesekẹsẹ ni o si ti mọ iru ẹniti emi nṣe.

Mo dobalẹ mo si ki pe Kabiyesi, on na ki mi o si bẹrẹsi ọrọ nisọ oni "Iwọ Ọ m ọ enia, iwọ ẹda Ọlọrun, ọjọ pe ti mo ti ri enia ti o laju silẹ bayi ti o si mọ ohun to nlọ ni agbegbe, gẹgẹbi emi ti si ṣe ri ẹ loni yi inu mi dun pupọ to jọ pe emi ko le fi ẹnu sọ" O di adọrin ọdun odin okan ti mo ti de si ilu yi.

Awọn Ọmọ Araiye korira wa pupọ wọn a si ma sọ pe awọn Afọjọ lo mba Ilu awọn jẹ, ọmọ ilu Lagbondoko ni emi nṣe. ni ẹ ba ilu Alupayida, nigbati mo wa ni ilu mi Ọlọrun tiṣe mi ni Ọ l ọ l a ati gbajumọ, mo si fẹran awọn ọmọ Ilu mi ṣugbọn nigbati awọn Ọmọ Araiye ri pe o ndun fun mi wọn wa ọna lati bajẹ, idi rẹ si ni yọn ti mo fi de ibi yi.

Mo kọkọ wa ni ilu yi lẹhin igba diẹ ti gbogbo rẹ ri bayi, ṣugbọn nigbati o ṣe ni awọn Ijọba agbegbe wa sọ nile Igbimọ Aṣofin wọn pe, a nba Ilu jẹ nitoripe a nlọrọ bara kiri, ṣugbọn nigbati a de ibiyi pẹlu awọn yoku mi abọ Ọlọrun to ni aiye to ni ọrun ti ko si gbagbe ẹnikẹni ki o ma ran wa lọwọ ki o si ma fun wa lo jẹ o jọ wa jọ, Ọlọrun gbọ adura wa mitotọ ẹnu yio si ya ọ pe lati ajule ọrun ni awọn Molẹka ti gbe o njẹ wa fun eyiti o ṣepe iwọ gan yio ri nigbati wọn ba gbe de laipẹ yi.

# Irohin Iku Alhadja Raolat Shitta-Bey

Iku - Mogajia Oloye Sulu Shitta Bey Sẹriku Musulumi Eko kan kakiri ni ọjọ Ọjọbọ ti ise ọjọ kejila oṣu yi Ariwo Ye! Ye!!si gbojigan l'agbole Shitta ni ita Matins ati li Kọta Ariyọ nibiti Ologbe na ku si nigbati o di ẹni ọdun marundinladọrin.

Gẹgẹbi eto ẹsin Imale nwọn gbe oku rẹ losin si itẹ Oku Suna lọjọ kanna ti o ku ẹsẹ awọn Alhaji, Oloye, Ọlọla Olowo ati Gbajumọ Eko ni o pe jọjọ si ibi aseyẹ Isinku rẹ Ọkẹ aimoyo enia gidi ni wọn.

Alhaji Imamu Deen agba Liadi Ibranim ni o sin Oku na ọpọlọpọ awọn Imamu ni o si ran lọwọ awọn ẹbi oku na pa pa Ọgbeni Shamsideen Shitta Bey Olori Ẹgbẹ Kila E k o na wa bi wọsi owo fun awọn alabaṣẹye isinku na. Aṣẹye isinku na d n o larinrin. Irohin koto afojuba ni.

Ọmọluwabi ni Alhadja Raolatu nigba aiye rẹ, o la wọ pupọ, o si ni oyaya pupọ. On ni olori awọn Alhadja Eko. Lọjọ Jimẹ-Jimọ ni o si ma nṣẹ ase fun awọn Alhaja ẹgbẹ rẹ ki Edumare dari ẹṣẹ rẹ jin ki o si gbe e si a fẹfẹ rere.

(Olori awọn Alhadja Eko ku).

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI A NPE NI:-

## "UROXAL"



Fun Itoju tabi fifọ Apo Ile Itọ Kidney - Bladder fun Ọkunrin ati Obinrin bi awọn amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu Ehin didun eri ile tabi itọ-jijo enia, itọ riru, rukuruku Pipọn tabi rirun, lakuregbe, Ibara di wiwo, orunkun, ọwọ, ẹsẹ Ejika wiwu tabi riro.

Ara sisan, titobiju, aiko le gbe ara konkọn tabi kiakia, didaji loru nigbakugba, ati orisirisi awọn aisan tabi amodi ba wọnyi ni egbogi ejebidan yi yio wo ṣan lara rẹ ni kia kia ti alafia yio si de si ọ. Meji rẹ ko si ni Ilu Naijiria nitorina ṣọra ki awọn eleru tabi awọn oni rọbirọbi ma ta orisi omiran ti ko ni lari fun ọ, maṣe gba rara o!

Owo rẹ jẹ Sile Mẹfa abọ 6/6d owo ọkẹ sile meji abọ (2/6d)

Bere Egbogi yi ni Ṣọbu awọn Saro ti wọn npe ni:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

GBANGBA DEKUN!! KEDERE BEWO!!!




## PORAL

OLUBORI EGBOGI "IKỌ'

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ọ lẹnu fun nkọn bi ọdun kan tabi jubẹ lọawọn egbogi rọbirọbi ko le se iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ ṣe Ofo mọ

Bere fun egbogi awọn ara Ilu Faranse ti wọn npe ni 'PORAL" ojulowo haunhaun, atamatase egbogi fun Ikọ here, Ikọ tutu, Ikọ ọna ọfun, Ikọ Igbaaiya, Ikọ lile, Ikọ" ti ọ ma mu enia tu kẹlẹbe nigbakugba lati inu "Ifun wa (Lungs) tabi ti o ma nmu enia ru pẹlu. Bi o ba dan Igo kan egbogi PORAL yi wo, Iwọ na yio ri iyatọ ninu ara rẹ ni kiakia, Igbaaiya tabi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro, "IKỌ" rẹ yio si san patapata, iwọ yio ma jẹun daradara iwọ o si sun fọnfọn pẹlu Alafia de.

Bere egbogi yi ati awọn orisirisi Egbogi Ikọ miran ni Ṣọbu awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lages, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA IBADAN.
ADEBỌGUN PATENT MEDICINE STORES
APATA AIYERAIYE STREET, ADE ỌYỌ IBADAN

## OBẸRẸ LATI OJU EWE KARUN.

Kiṣe ẹrẹkẹ ebu ni yio ṣe wa lore bikoṣe pe ki a panupọ ki a ṣe ara wa lọkan nipa gbigba Ipinlẹ ki a ba le bọ loko ẹru Ilọrin. Bi ede wa ba ye ara wa dada ni, gbo gbo ẹrẹkẹ ebu to jẹ wipe anbu ara wa lati ẹhin wa kole ran wa lọwọ bikoṣe Ipinlẹ tiwa lotọ ni o le ran wa lọwọ. Ẹnu gbogbo wa nilati dọgba dada ki ato la ọrọ Ipinlẹ gbigba mọlẹ, lai jẹ pe ẹnu wa dọgba ati Ilẹ Igbomina, Ọffa ati Ekiti a ko le bọ loko ẹru sulu Gambari lailai.

Mo lẹ ki o ye ọtun ati osi wipe kosi ẹniti ko fẹ ki agba Ipinlẹ ati Olomi ati Ọlọpẹ ilẹ Igbomina, Ọffa ati Ekiti, ṣugbọn ẹjẹki a ye sọ wipe ẹgbẹ Ọlọpẹ ni yio fun wa ni Ipinlẹ na. Nitsiyi ti gbogbo ilu Ajassẹpo, Ọffa Agbele Oro ati orẹ mi Ọdẹkunle ti di ọmọ olomi, mo ro wipe ọrọ Ipinlẹ gbigba na yio jẹ Irọrun fun gbogbo wa.

Esi yin ni mo nduro fun ki a le ko ara wa lọ ba ẹniti yio ba wa gba Ipinlẹ na.

EYI NI IDAHUN AWON IBERE TO WA NI OJU EWE KẸTA.

(1) Owo Ẹru (2) Mohammed (3) Ọlabisi Ajala (4) Kenneth Dike (5) Marry Slessor (6) Delhi (7) Ọdun 1849 (8) 1472 (9) 1931 (10) Lord Lugard (11) Kano, ati Timbuctoo (12) Dosunmu ọmọ Akintoye lọdun 1861 (13) (Frootown 1791) (Liberia 1822) (14) Abraham Lincoln (15) Loko ireke pẹlu oko Taba (16) Ohun ti o jẹki Asia, Amẹrika ni irawọ 48 nipe orilẹ-ede 48 ni wọn papọ. (17) (Nigeria) gusu Afirika,-Amẹrika (18) Norweigh, Sweedeen, Japan, England, (19) Tọfi, Ovaltine (Abẹla), Ọṣẹ, Bata, Tyre, epo moto (20) Nitoripe ohun lojọ ti Azikiwe di Gomina agba ilẹ Naijiria


BERE EGBOGI JAMANI AJIDEWE TONIKI TITUN TI O ṢẸṢẸ DE TI WỌN NPE NI:-

"DYNAMI REN" TONIKI

EGBOGI AJEBIDAN FUN AGBALAGBA ỌKUNRIN GBOGBO




Dynamiren jẹ Ojulowo Egbogi Ajidewe haunhaun ti awọn Jamani ti nṣe wa fun tita ki ogun (War) ti awọn Gẹsi pẹlu wọn to ṣẹlẹ. Lẹhin igbana a ko ri irufẹ egbogi ajidewe ti o lagbara gidigidi ti iṣẹ rẹ si daju bẹ yẹn mọ ni ilu Naijiria, eyi lo mu wa ranṣẹ si awọn Ogbologbo Dọkita wa ni ilu Jamani pe ki wọn ṣe iwadi awọn elegbogi "Dynamiren" bi wọn ba si mbẹ laiye. Wọn si da esi pada wipe wọn nbẹ atipe egbogi na ti a nfẹ lọdọ wọn wa pẹlu. Eyi mu inu wa dun pupọ julọ nitoripe awọn Onibara wa mọ daju wipe kosi asanu ninu gbogbo egbogi wa rara. Egbagbeje irufẹ rẹ wa kakiri ṣugbọn bi ti eleyi kọ. Bi arẹ ara ba mu ọ, nigbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe ti o ko ba le jẹun daradara, tabi ki o ma le sun de ọkọn lọsan tabi loru tabi awọn "Iṣan ara rẹ gbogbo" ko ba ṣiṣẹ daradara arẹ-Emi (breath) inu ko ba gunle daradara to nitoripe iṣẹ tabi wahala ṣiṣe ko "NJẸ" fun awọn ailera gbogbo wọnyi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun lọ si oe de adọrin tabi jubẹ lọ mọ daju pe "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara rẹ du Ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹrẹ si dan pada. Ara rẹ yio ma gbe konkon nigba kugba "Arẹ" nigbakugba yio salọ patapata pẹlu.

Igbadun ati Alafia yio de si ọ.

Bere egbogi na ni Ṣọbu awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS PHONE: 20278.

ADEDUN CHEMIST
4, WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA IBADAN.
ADEBOGUN PATENT MEDICINE STORES
APATA AIYERAIYE STREET, ADE ỌYỌ IBADAN



Read The IROHIN IMOLE every week. It is a Yoruba Weekly Paper that will provide you with more News more Pictures and more Fun. It will enlighten, entertain and inform you. Always read:-

"Irohin Imole"

The most exciting controversial Yoruba weekly Paper


O BERE LATI LOJU EWE KẸTA

Nigbati o wa ya baba wọn wa ku, wọn wa ranṣẹ si eyi Ọkunrin pe Baba wọn ku, o ni Baba on kọ lo ku. Eyi obinrin ba wa ile ṣe oku baba wọn. Nigbati wọn ṣe oku tan, eyi okunrin ti ko wa le wa ṣe oku ba ne.

Owo ti tan lọwọ rẹ, o wa ranti ile wa yi, nigbati o de ile o ni baba on da?, wọn ni baba rẹ ti ku, oni kini ṣe ti wọn ko ranṣẹ si on, eyi aburo ba ta kọ, pe on ṣefun ẹ pe baba awọn ti ku.

Ki a ma fa ọrọ gun lo titi wọn ba pin ogun baba wọn, eyi okunrin ni, eyi ti wọn pin fun o o kere, ni oba pa aburo obinrin nitori ogun baba wọn. Eyi to ku di ọse to nbọ o, lọkan si mo ki gbogbo ẹnyin onkawe Irohin Imọle.

## Awon to lo wa Owo ati Ise wa sile Nigeria



Erin ti a nwo ninu aworan yi ni aworan ti awọn ara ilu Denmark gbẹ ti won si gbe kalẹ ni ibikan ti nwọn npe ni ẹnu odi Elerin ti nwọn ngba wọ ilu iṣẹ ibiti nwọn nse oti.

Awọn ti a nwo nisalẹ aworan na ni awọn ara ilẹ Nigeria ti o lo wa iṣẹ-ṣe wa ati owo wa fun ilẹ Nigeria.

Awọn oyinbo ti o duro lẹgbẹ Zana Dipcharima ọga agba olotu iṣẹ oti bia na ọgbẹni Hamstrup Clemnsen.

(O BERE LATI OJU EWE KINE)

Awọn enia merindinlọgbon tia yen na ni wọn yi, Ọba Alake Abeokuta ei alaga, Oshile oke ona, Ọba Agura, Ọba Olowu, Ọba Ibara, Osin ẹgba, Ekẹrin Egba Seriki Egba ashipa ẹgba, Aro ẹgba, Lisa, ẹgba Ọdofin ẹgba, 'Bala ẹgba, Apena ẹgba Oloye Toye Kuti, Senator Y.M. Abudu, Alhaji A. Adeleken, Alhaji A. Akinto. Alhaji J.S. Adeniyi Olotu ile ẹkọ giga Abeokura, ati Ọgbẹni Owolabi Kolawole ẹniti on dari eto inawo ile Igbimọ na.

## Awon Omo Akeko City College Pada Sile Eko



Nigbati Ọgbeni Blankson ri oye pe awọn ọmọ akẹkọ kọ ile iwe sile, o pe wọn jọ, o si ba wọn sọrọ pe ki nwọn pada sidi ẹkọ wọn, on yio ri si ẹdun okan wọn.

Ati le gbọ wipe awọn ọlọpa ti duro pe boya agan ija yio bẹ. Awọn ọmọ ile ẹkọ na la nwọ nigbati nwọn pada si ile ẹkọ wọn. Akọwẹ awọn ọmọ akẹkọ ni a nwo yio o.

AGED MEN MUST TAKE.

## SENGOVAN

(Extra Strong For Vitality and Energy)
IMMEDIATE RESULT

Sengovan is the most valuable Product known all over the Wold since many years and used by all men who look for New Life.

Sengovan is based on latest scientific experiences. It is a pharmac. Composition of male Germo-Glands and Hypopys' Cerebi together with an exactly dose of Lecihine and some other efficacious of high quality.

Sengovan is a remarkable remedy which gives marvellous results within half an hour after use.

That is The Great Advantage Against All Other Similar Rejuvenation Cure.

It is a harmless but most efficacious preparation against sexual weakness, sterility and impotence, against nevous troubles and loss of youth and energy.

Sengovan gives marvellous result and-most important fact-not only marvellous, but almost immediate result in all case of Steriltiy, Sexual exhaustion and Importance. Again Sengovan is a most valuable nerve tonic.

At the same time Sengovan is free from poison.

Sengovan may be use without any fear of unpleasant consequences enslavement to habit.

DIRECTION: 1 to 2 pills to be taken half an hours before result is wanted. Try whether 1 only Pills is sufficient for your constitution, if so do not take more pills at one time.

Imported & sold by:

HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES
26, Bishop Street Phone: 23457
LAGOS

## Albert Adeoye se ase idagbere

Itohin ko to afojuba ni ase idagbere ti Ọgbeni Albert Adeoye onisowo pataki ati akapo owo Egbẹ Ọmọ Esiẹ li Eko se fun Iyaafin Emioye Adeyo, aya ọmọ rẹ ti o lọ si ilu Oyinbo lenulọlọyi lati lọ kọ isẹ. Ni ile rẹ ti o wa ni Idumagbo ni Ọgbeni Albert Adeoye gbe ti se se alarintin na. Oloye Lamidi Kalejo keji, Olumegbon Ajaye Eko ni o se alaga, o si sọ bi Ọgbeni Stephen Onaọlapọ ọkọ Emioye ti se jẹ ọmọluwabi si o ni ọkọ Emioye wa ni ilu Oyinbo kọ ẹkọ ise lọya o si sọrọ ibukun fun ọkọ ati aya. Ajẹti ati a muti ni awọn a'aba ṣẹyẹ ọjọ na fi ọti ati onje se nwọn le ni igba enia. ti onje ati ọti ọjọ na se lalejọ nitoni rẹpẹtẹ.

## Wanted

2 Advance Apprentice Printers and 1 JournyMan. Apply to:-
MODUPE PRINTING PRESS
16, Bamgbose Street Lagos.

## PAYAL (IPARA)

Ati awọn orisirisi omiran irufẹ rẹ jẹ ojulowo Egbogi kokoro ti o lagbara gidigidi fun "Ipara" ti awọn ailera tabi amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu ni ode ara. Ara, ọwọ tabi ẹsẹ bibun tabi yiyun nigbakugba Alefọ. Egbo Esọ orisirisi tabi ti ojẹ rẹ ti pẹ bi adajinọ Egbo, Ekusẹ tabi Lapalapa, Eli, Ara sisan, Akọ Inarun, Sobiya Afọju ati orisirisi arun "ARA" miran gbogbo.





Gbiyanju lati dan egbogi kokoro titun si awọn ara Ilu Tatanbulu se ti wọn npe ni "PAYAL" wo larin ijọ mẹta iwọ na yio ma rohin rẹ fun awọn elomiran pẹlu. Egbogi ipara yi ki se awọn rọbirọbi ti wọn nta kakiri ilu ni owo pọku. Ojulowo egbogi arun ara haunhaun ti ko si sisẹ iye meji ninu rẹ eleyi si yatọ patapata si awọn egeremiti adimọwọ ti wọn nta kakiri Igboro ati ni agbe-reko gbogbo pẹlu. Orisi meji rẹ lowa. Kekere ati Nla Bere Egbogi Ajẹbina PAYAL yi ni Ṣọbu awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA IBADAN.
ADEBOGUN PATENT MEDICINE STORES
APATA AIYERAIYE STREET, ADE ỌYỌ IBADAN

Printed and Published by DUPE PRINTING PRESS (6, Bamgbose Street Lagos, Phone 21985 Olotu. E. A. Adeniji 31, Tẹjuoṣo Street Surulere YABA.

FUN OWO IROHIN IMỌLẸ ỌDUN KAN
EKO:- Ṣile Mẹjọ ati Kọbọ Mẹjọ (8/8d)
Ilumiran ni Naijiria ati Oke Okun:-
Ṣile mejila ati Kọbọ Mẹfa (12/6d)